**Ijọ́ Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu**
**Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàìjíríà**
**ÌSÌN OMI MÁNNÀ**
**Kókó Àdúrà – ÌWÒSÀN PÍPÉ (4)**

**Ìjẹ́wọ́: Deutẹ́rónómì 7:15:** Olúwa yóò sì gba àrùn gbogbo kúrò lọ́dọ̀ rẹ, kì yóò sì fi ọkàn nínú àrùn búburú Égíptì, tí ìwọ mọ̀ sí ọ lára, ṣùgbọ́n òn ó fi wọ́n lé ara gbogbo àwọn tí ó kórira rẹ.

**Orin Ìyìn àti Ìjọ́sìn**

1. Gbogbo iná àìsàn tó n dá ayé mi lóró, afẹ́fẹ́ Ilà-oòrùn, fẹ́ wọn dànù, ní orúkọ Jésù.
2. Olúwa, jẹ́ kí iná Ẹ̀mí Mímọ́ yọ gbòngbò ìpọ́njú dànù kúrò nínú àgọ́-ara mi, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo agbára ọlánrẹ́yìn tí wọ́n yàn lòdì sí ayé mi, kú nípa iná, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo odù àjẹ́ tó n ṣe àláfíà mi, gba iná, ní orúkọ Jésù.
5. Olúwa, jẹ́ kí ìmọ́lẹ̀ mi bẹ́ jáde, kí ìlerá mi sì sọ jáde ní kánkán, ní orúkọ Jésù.
6. Mo ru àmì àpá ẹ̀jẹ̀ Jésù lí ara mi, nítorí náà, kòsí ìpọ́njú tí yóò dúró nínú ibùgbé mi, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo àṣẹ àjẹ́ tí wọ́n kọ lòdì sí ayé mi, parẹ́ nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
8. Gbogbo ẹ̀mí tó n jẹ mí láti inú, kú, ní orúkọ Jésù.
9. Olúwa, nípa agbára Ọlọ́run Èlíjàh, jẹ́ kí àlàjá tíkòwọ́pọ̀ farahàn nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
10. Bàbá mi, jẹ́ kí Ọmọ Aládé Àláfíà sọ̀rọ̀ àláfíà sí gbogbo ìjì nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.

11. Gbogbo irúgbìn àìsán nínú àgọ́-ara mi, gba iná, ní orúkọ Jésù.
12. Gbogbo ìránṣẹ́ àìsàn nínú àgọ́-ara mi, jáde, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
13. Olúwa, jẹ́ kí a ra ayé mi padà kúrò lọ́wọ́ agbára ìrora, àìsàn àti ìpọ́njú, ní orúkọ Jésù.
14. Olúwa, jẹ́ kí agbára ikú àti ipò òkú tí ó wà nídì àìsàn tó farasin nínú àgọ́-ara mi pàdánù ìgbámú wọn, kí wọ̀n sì kú, ní orúkọ Jésù.
15. Èmi kòní kú bíkòṣe yíyè láti máa ròyìn àwọn iṣẹ́ Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
16. Gbogbo omi ìpọ́njú àìsàn tó n ṣàn sínú ayé mi láti ilé bàbá mi, di gígé dànù, ní orúkọ Jésù.
17. Ìpéjọpọ̀ búburú ìyówù lòdì sí ìwàláàyè mi, túká, ní orúkọ Jésù.
18. Olúwa, nípa agbára nlá Rẹ, túmisílẹ̀ kúrò nínú gbogbo ṣẹkẹ́ṣẹkẹ̀ ìkùnà, ní orúkọ Jésù.
19. Bàbá, nípa ọ̀rọ̀ májẹ̀mú Rẹ, dìde nínú ìrúnú Rẹ, kí O sì bá ajẹnirun ayé mi wí, ní orúkọ Jésù.
20. Mo kọ gbogbo ọ̀rọ̀ búburú tí wọ́n ti sọ lòdì sí ìwàláàyè mi rí, nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
21. Mo pàṣẹ wí pé, ipòkípò tí mo wà báyìí kì yóò jásí ikú fún mi, dípò èyí, yóò yọrí sí ìyìn, ní orúkọ Jésù.